# ORÍ ÒKÈ INÁ ÀTI IṢẸ́ ÌYANU

Olú Ilé Iṣẹ́ Ìránṣẹ́, Ìpínlẹ̀ Èkó, Nigeria.

## OSÙ KÍNNÍ, ỌDÚN 2023

**Agbára Gbọ́dọ̀ Pàrọ̀ Ọwọ́**

**ÌTÚSÍLẸ̀ ÌDÍLÉ (4)**

## OṢÙ KÍNNÍ, ỌDÚN 2023

| | |
|---|---|
| 7:00 am – 7:05 am | Àdúrà ìbẹ̀rẹ̀ |
| 7:05 am – 7:20am | Orin Ìyìn àti Ijọ́sìn |
| 7:20 am – 7:35 am | Ijẹ́rì |
| 7:35 am – 7:45 am | Wákàtí Ìṣìpẹ̀ Àdágbà |
| 7:45 a m – 8:45 am | Iṣẹ́ Ìránṣẹ́ |
| 8:45 am - 9:00 am | Ọrẹ àti Ìparí ìpàdé |

## GBÉ OLÚWA GA PẸ̀LÚ MI

1. Gbé Olúwa ga pẹ̀lú mi,
Ẹ̀yin ènìyàn Rẹ,
Kí gbogbo ẹ̀dá alàyè,
Ma yọ̀ l'órúkọ Rẹ̀,
Fún ìfẹ́ tí Ó n fihàn,
Fún ìsinmi l'ọ́kàn wa,
Fún igbàlà kíkún Rẹ̀,
Tìrẹ lọpẹ́.

Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa títí láíláí,
Àní, títí láíláí,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa f'ọpẹ́ fun,
Kí gbogbo wa yin orúkọ,
Olúwa wa títí láíláí,
Àní, títí láíláí,

2. Ẹ̀yin fún ìwà-mímọ́ Rẹ,
Fún ore-ọ̀fẹ́ Rẹ,

Kọrin ìyìn fún ẹ̀jẹ̀ Rẹ,
Tó fi rà wá padà,
Ìfẹ́ ló fi wá wa rí,
Nínú ìrà ẹ̀sẹ̀ wa,
Ó f'ọ̀nà ìyè hàn wá,
Ẹ f'ọpẹ́ fun.

3. Èmí 'ba l'ẹ́gbẹ̀rún ahọ́n,
Nkò lè ròyìn ná tàn;
Ìfẹ́ Rẹ̀ sí mi pọ̀ jọjọ,
Ago 'bùkún mi nkún,
Ore-ọ̀fẹ́ tí kì yẹ́,
Àláfíà bí odò,
Lát'ọ́dọ̀ Olùbùkún;
Ẹ fọpẹ́ fun.

## GBỌ́! ÌRÓ LÍ ÒPÓPÓ AYÉ

1. Gbọ́! ìró lí òpópó ayé,
Bí ti ìgbì omi òkun,
Tí nfi agbára rẹ̀ ru s'ókè,
T'ó sì nkọlu èbúté.

Gbọ́! bí ẹṣẹ̀ ọmọ ogun,
Bí wọ́n ti nrìn lọ lí ọ̀nà nà,
Àrẹ́ mú wọn fún 'sẹ́ àt'ìrìn àjò,
Àti ìjà kíkorò;

Ṣùgbọ́n wọ́n gbàgbọ́, wọ́n tẹjúmọ́
Ọ̀nà ná t'áwọn mímọ́ ti nrìn,
Bí wọ́n ti nlọ ní 'gbàgbọ́
Wọ́n ndàgbà n'nú Ọlọ́run alàyè

2. Wọ́n ntẹ̀síwájú pẹ̀lú ‘gbàgbọ́
Tí ẹ̀kọ́kẹ́kọ̀ kò lè mì;
Wọ́n gbàgbọ́ pé ọ̀rọ̀ Ọlọ́run
Lè pèsè f’àìní gbogbo.

3. Dàpọ̀ mọ́ wọn, àyéwà síbẹ̀
Dúró de ‘bùkún Ọlọ́run:
Òun ni ‘rètí gbogbo àgbáyé
Láti ṣiṣẹ́ òdodo.

## **ỌRỌ̀ AGBÁRA**

1. Gbogbo ìgbìmọ̀ àti ìmọ̀ràn búburú, tó lòdì sí ìfarahàn ògo mi lọ́dùn yìí, yóò kùnà gẹ́gẹ́ bí ó ti rí fún Àhítófẹ̀lì, ní orúkọ Jésù.
2. Ifòróróyàn fún ìfarahàn ògo, ayé mi ṣí sílẹ̀ fún ọ lọ́dún yìí, wọlé wá, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo ibi tí mo bá lọ lọ́dún yìì, ààbò àtòkèwá yóò bòmí, ní orúkọ Jésù.
4. Lọ́dún yìí, ẹnubodè àánú, ojúrere àti ìfarahàn ológo yóò ṣí sílẹ̀ fún mi, ní orúkọ Jésù.
5. Nípa àánú Rẹ, Olúwa, jẹ́ kí ayé mi ṣàfihàn ògo Rẹ lọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.
6. Gbogbo ìdíwọ́ tó farasin àti ìdènà sí títẹ̀síwájú mi lọ́dún yìí yóò gba ìparun, ní orúkọ Jésù.
7. Ojúrere àti àánú àtòkèwá kì yóò fi ayé mi sílẹ̀ jálẹ̀ ọdún yìí, ní orúkọ Jésù.

## **ÀDÚRÀ ÀDÁGBÀ – ÌJẸ́WỌ́: ORIN DÁFÍDÌ 91**

1. Ọlọ́run, dìde, kí O sì fàtu ohunkóhun tí O kò gbìn sínú Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
2. Ọlọ́run, jẹ́ kí iná ìsọjí bà lé Orí Òkè Iná àti Iṣẹ́ Ìyanu, ní orúkọ Jésù.
3. Gbogbo agbára òkùnkùn tí wọ́n yàn láti gbógun ti àṣeyọrí mi lọ́dún yìí, ṣubú lulẹ̀ kú, ní orúkọ Jésù.

4. Gbogbo kòtò tí àwọn ìránṣẹ́ ikú gbẹ́ fún ayé mi yóò gbé àwọn tó gbẹ mìn, ní orúkọ Jésù.
5. Gbogbo ìpinnu, ìdájọ́ àti gbólóhùn àjọ àjẹ́ lòdì sí ògo ayànmọ́ mi lọ́dún yìí, rún wómúwómú, ní orúkọ Jésù.
6. Iná Ẹ̀mí Mímọ́, yọ́ dànù, gbogbo gbólóhùn tí wọ́n yàn láti fàmílulẹ̀ lọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.
7. Níbo ni Olúwa Ọlọ́run Èlíjàh wà? Dìde, ṣèdájọ́ gbogbo ahọ́n tí wọ́n yàn láti dámilẹ́bi lọ́dún yìí, ní orúkọ Jésù.

## ÀDÓ Ọ̀RỌ̀ NÁÀ

**2 Kọ́ríntì 9:8** Ọlọ́run sì lè mú kí gbogbo ore-ọ̀fẹ́ ma bísi i fún nyín; kí ẹ̀nyin, tí ó ní ànító ohun gbogbo nígbàgbogbo, lè ma pọ̀ si i ní iṣẹ́ rere gbogbo:

**Jeremíàh 29:11** Nítorí èmi mọ̀ ìrò tí mo rò sí nyín, li Olúwa wí, àní ìrò àláfíà, kì sí íṣe fún íbi, láti fún nyin ní ìgbà ìkẹ́yìn àti ìrètí.

**Fílíppì 4:19** Ṣùgbọ́n Ọlọ́run mi yóò pèsè ní kíkún fún gbogbo àìní nyín, gẹ́gẹ́ bí ọrọ̀ rẹ̀ nínú ògo nínú Krístì Jésù.

**Rómù 15:13** Njẹ́ kí Ọlọ́run irètí kí ó fi gbogbo ayọ̀ òn àláfíà kun nyín ní gbígbàgbọ́, kí ẹ̀nyin kí ó lè pọ̀ ní irètí nípa agbára Ẹ̀mí Mímọ́.

**Orin Dáfídì 103:1-4:** Fi ibùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, àti gbogbo ohun tí ó wà nínú mi, fi ibùkún fún orúkọ Rẹ̀ mímọ́. Fí ibùkún fún Olúwa, ìwọ ọkàn mi, má sì ṣe gbàgbé gbogbo ore rẹ̀: Ẹnití ó dárí gbogbo ẹ̀ṣẹ̀ rẹ jì; ẹnití ó sì tán gbogbo àrùn rẹ, Ẹnití ó ra ẹ̀mí rẹ kúrò nínú ìparun; ẹnití ó fi ìṣeun-ìfẹ́ àti ìyọ́nú dé ọ lí adé.

**Orin Dáfídì 16:11** Ìwọ ó fi ipa ọnà ìyè hàn mí; ní iwájú rẹ li ẹ̀kún ayọ̀ wà: lí ọwọ́ ọ̀tún rẹ ni dídùn-inú wà láíláí.

**Orin Dáfídì 118:24** Èyí lí ọjọ́ tí Olúwa dá: àwa ó ma yọ̀, inú wa yóò sì ma dùn nínú rẹ̀.